MAMA-TONE
C.M.T. fun
ABOYUN, ABIYAMỌ ATI OBINRIN MIRAN.
Mamatone je Tonic Iyabiye ati Gbogbonse Kosemani fun gbogbo obinrin papa lasiko oyun fun: Ailera, Eti, Oyi, Aya ririn, Jedijedi, Aile jeun, Inu ririn, Inu gbogbe-na, Iwora. Ehin didun ati Bebe.

Irohin Yoruba

A Newspaper of the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd

VOL. XIV NO. 687 JULY 28—AUGUST 3, 1958. KỌBỌ MEJI (2D.)

OWE

Bi agbalagba ba nyọ ilẹ da, ohun buruku a ma a yọ ọ ṣe.

IJỌBA PARI ADEHUN IṢẸ ỌKỌ OFURUFU

EKO.—NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi ni awọn Alakoso Iṣẹ-owo ọkọ oju-omi ati ti ọkọ-ofurufu ti yio ṣe alabapin pẹlu iṣẹ Ọkọ-ofurufu ti Ijọba fẹ da silẹ ni ọjọ kini oṣu kẹwa ọdun yi wa fi ọwọ si Iwe-adehun iṣẹ titun na pẹlu Oloye S. L. Akintọla, Minista Alamojuto Eto Iṣẹ Waya ati ti Ọkọ-ofurufu Apapọ Ijọba Naijiria ni inu Gbọngan Ile Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria.

Awọn onişẹ-owo nla mẹta na ni Ọgbẹni John H. Joyce, ti iṣe Alakoso Iṣe Onişowo Ọkọ-oju-omi "Elder Dempster Lines Ltd."; Ọgbẹni John Booth, Alakoso Iṣẹ Ọkọ-ofurufu "BOAC" ati Ọgbẹni Baker-Beall, Ọga-Iṣẹ Ọkọ-ofurufu "WAAC".

Ọlọla James Robertson, Gomina-Agba Apapọ Ijọba Naijiria ni o ṣe Alaga Aṣeyẹ-Eto Ifọwọsi-Iwe-Adehun na. Alaga na sọ wipe: "ọjọ iranti nla ni ayajọ ọjọ oni ninu itan Naijiria". Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria si gba Eto-Adehun na tayọtayọ, o ni: "ọjọ nla ni ọjọ oni jẹ fun ilu yi."

Lẹhin na ni Oloye S. L. Akintọla wa ṣe alaye gbogbo wahala ati akitiyan ti gbogbo awọn enia wọnyi ti ṣe ki iṣẹ na to le yori si dada bayi. Oloye na tun ṣe alaye wipe owo ti nwọn yio fi bẹrẹ owo iṣẹ ọkọ-ofurufu yi jẹ ọodun-okẹ ponun (£6,000,-000) eyi ti Naijiria yio da sinu okowo na yio si ju idaji lọ.

Oloye na si tun sọ siwaju pe, Iṣẹ Ọkọ-ofurufu titun ti Naijiria fẹ da silẹ yi yio jẹ iranlọwọ fun ilu Saro (Sierra Leone) ati Gambia, yio si tun wa ọna bi ifọwọsowọpọ yio ti ṣe wa pẹlu Ghana. Oloye Akintọla si ki awọn Ọga Onişowo ti o fọwọ sinu adehun gẹgẹbi alabapin ninu iṣẹ na, o si yin wọn pupọ fun igbẹkẹle ti nwọn ni ninu Naijiria. O si fi ọkan gbogbo awọn oşişẹ ọkọ-ofurufu ti yio ma a sişẹ ninu iṣẹ na pe, gbogbo wọn ni yio ma a fi igbadun ṣ'ayọ bi iṣẹ yi ba bẹrẹ.

Eyi ni aworan awọn ti o fọwọ si Iwe-adehun iṣẹ ọkọ-ofurufu ti Apapọ Ijọba Naijiria fẹ da silẹ ni ọjọ kini oṣu kẹwa ọdun yi. Awọn na ni Ọgbẹni John H. Joyce, Alaga awọn Onişowo Ọkọ-oju-omi "Elder Dempster Lines Ltd."; Oloye S. L. Akintọla, Minista Alamojuto Ile-Iṣẹ Waya ati ti Ọkọ-ofurufu Apapọ Ijọba Naijiria; Ọgbẹni John Booth, Alakoso Iṣẹ-Ọkọ-ofurufu "BOAC" ati Ọgbẹni R. W. C. Baker-Beall, Alamojuto Iṣẹ Ọkọ-ofurufu "WAAC". Iwe Adehun na ni nwọn nfọwọsi yi.

Ijọba mba Balẹ Abule Odogo ṣẹjọ pe o paṣẹ pe ki nwọn pa ole

ILARO.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu yi ni awọn ọlọpa ko awọn ọdaran mẹsan, Salmi Arigbajo, ẹni ọgọta ọdun ti iṣe Balẹ abule Odogo ni Ilaro; Mọmọdu, ẹni ọdun marundiladọta; Surakatu, ẹni ọdun marundilogoji; Jimọh Adeoye, ẹni ọdun mẹtadiladọta; Alieru, ẹni ọdun marundilogoji, Gbadamosi, ẹni ogoji ọdun; Senni, ẹni ọdun mẹtadilogbọn; Mutairu, ẹni ọdun mejidiladọta ati Aşiru, ẹni adọta ọdun ti o nşişẹ aşode-oru wa siwaju Adajọ Kotu Kekere Ilaro fun ẹsun pe nwọn ditẹ lati pa enia.

Ẹsun Ọgbẹni Sunday Paul, ọlọpa ti o mba awọn ọdaran na rọjọ kkọ fi wọn sun ni pe nwọ lu Garuba Sokoto, alagbaro-oko kan ni abule Ebutero, nwọn dọgbẹ si i lara, o fi iyẹn silẹ nigbati o ri i pe iyẹn ko ba ẹsẹ wọn mu, o wa şẹşẹ mu ẹsun wa siwaju Adajọ pe, awọn ọdaran yi sa ẹniti o wa "ẹjọ sun yi logbẹ yannayanna.

Wo oju ewe kejila

Ẹgbẹ Afẹnifẹre bori Ẹgbẹ Olomi ni Ilu Jos ati ni Idoma

OTURKO.

EGBẸ Afẹnifẹre dapọmọ Ẹgbẹ United Middle Belt Congress (AG/UMBC) ni o ṣẹgun awọn Ẹgbẹ Olomi (Northern People's Congress) ti iṣe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ninu idibo ti nwọn ṣe ni aipẹ yi wọle awọn Igbimọ ilu gbogbo ti o wa ni Ẹkun Ilu Idoma.

Ayọrisi idibo na ni pe ninu awọn Igbimọ ilu mẹdọgbọn ti nwọn dibo fun ni Ẹkun Ilu Idoma na, mejilelogun ni o bọ sọwọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre dapọmọ Ẹgbẹ UMBC, mẹta pere ni o bọ si ọwọ awọn Ẹgbẹ Olomi (NPC).

Eyi ni iṣẹgun nla keji ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre dapọ-mọ Ẹgbẹ "United Middle Belt Congress" ni ni agbegbe ilu agbedemeji Ipinlẹ Ariwa (Middle Belt). Nitoripe nigbati ayọrisi gbogbo ibo ti nwọn di fun gbogbo awọn ilu Ẹkun Jos jade, ninu Igbimọ Ilu mẹrindinlogun, mẹrinla ni o bọ sọwọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre dapọ-mọ Ẹgbẹ UMBC ẹyọkan pere ni o bọsi ọwọ awọn Ẹgbẹ Olomi (NPC) ọkan ti o ku nilẹ ni nwọn ta l'omi, dọgba-dọgba ni awọn aşoju ti awọn Ẹgbẹ mejeji ni nibẹ.

Ayọrisi idibo awọn ilu Ẹkun Jos ati ti Idoma yi fi han gbangba pe, awọn ara ilu agbedemeji Ipinlẹ Ariwa (Middle Belt) ko fẹ Ijọba Ẹgbẹ Olomi ni arin awọn mọ rara, ni nwọn ṣe faramọ ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre nitoripe nwọn ti mọ daju gbangba pe Ẹgbẹ Afẹnifẹre nikan ni o to o tẹle gba Ominira Ijọba fun gbogbo Apapọ Ijọba Naijiria.

Ayọri iwadi Ibẹru Ẹya ilu keekeeke yio jade ni pari oṣu yi

LỌNDỌNU.

NI ọjọ Aje ti işe ọjọ kọkanlelogun oşu yi ni Ọgbẹni Alan Lennox-Boyd, Aşoju Ijọba Gẹẹsi fun awọn ilu abẹ Ijọba Gẹẹsi sọ ninu Apejọ Igbimọ Apapọ Ijọba Gẹẹsi pe on ni ireti pe ayọrisi iwadi ibẹru awọn ẹya ilu kekeek Naijiria ti nwọn şe laipẹ yi yio tẹ on lọwọ ki o to to ipari oşu yi. O si sọ wipe bi o ba ti nte on lọwọ ni on o ti jẹki nwọn tete tẹ ẹ.

Iya Ade Thanni ku

EKO.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oşu yi ni Iyaafin Muniratu Shekoni ti apele orukọ rẹ njẹ Mama Amuwo ku si ile rẹ ni Apongbọn Street, l'Eko lẹhin ti o ti şe aisan fun igbadiẹ, nigbati o di ẹni ọgọrun ọdun. Ni ọjọ keji ti o ku ni nwọn gbe oku rẹ lọ sin ni Itẹ-oku Musulumi ni Ẹpẹtẹdọ, iye awọn enia pataki-pataki ti nwọn ba wọn gbe oku na lọ sin fẹrẹ to ẹgbaa (2,000), Imam Agba Eko ni o şe isin ikẹhin fun un.

Awọn ọmọ oku, awọn bi Iyaafin Salamọtu-lai Awẹlẹwa Akodu ati Ọgbẹni Adebiyi Thanni, Ọga-agba Oniwe-irohin Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun (Principal Information Officer, Western Region) nawo pupọ, nwọn fi orişirişi onjẹ adindun ati orişirişi ọti tẹ gbogbo awọn alabaşeyẹ ọjọ na lọrun titi fi di ọganjọ oru ọjọ na.

Iya na jẹ olufọkansin enia nigba aiye rẹ, o si jẹ ọmọluwabi ni gbogbo aye. Ki Ọlọrun dari ẹşẹ rẹ jin in, ki O kẹ ẹ, ki O gẹ ẹ ki O si jẹki ẹhin rẹ dara.

Iya oninure, sunre o.

Ẹgbẹ Alakukọ ko feran Ọba ati Ijoye

OHUN ti o ṣẹlẹ laipẹ yi ni ile Igbimo Ijoba Ipinle Iwọ-Orun pe Ogbeni Olowofoyeku sọ pe, ki awọn oba ati Ijoye ma se ni emi ninu Igbimo Ijoba Ibile won mọ fihan pe Egbe Alakukọ ko feran awon Oba.

Nigbati awon Oba pasipa ba ri oyi nwon yio mọ ota won yato si ore won, ti o ba se pe Egbe Alakuko ni o nse Alakoso Ijoba Ipinle Iwọ-Orun ni nse ni nwon iba ma a f'oju ọla gbole. Ori ni awọn Oba je fun won kini wa se ti Egbe Alakuko fi ntako ifowosowopo ninu oran oselu pelu Ijoba Ipinlẹ Iwọ-Orun? Ikorira ati ijowu ni.

Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
BURAIMỌ KUDẸTI.
Erinmọ.

Iwe si Olọkun Irohin Yoruba

Ijọba, Ẹ ba pa iṣẹ agbero-mọto rẹ

EJOWỌ gba mi laye lati kesi awọn Igbimo Ijoba Ipinle ati Ijoba Ibile ki nwon ba wa mu oju to oran awon kan ti nwon nse orayo, ko-jọ agbe ko-jọ ole kaktri ilu, ti nwon so pe nwon nsise kan pataki. Awon onise ọlẹ ma ni awon agbero sinu mọto. Iwa ibaje ti won nhu si awon ero awomọto ko kere.

Eniti o dide ni ile re lati wọ mọto, ti o ba de idikọmọto ki o lọ wọ mọto ti o ba wu u wọ, sugbọn awon agbero yi pelu awon ọmọ jaguda ni ndi imọ lu gbe eru eleru salọ, nigbamiran nwon a ko eru won sinu mọto onidana, awon ti i ma a wa mọto lọ pade awon ọlọsa ninu igbo.

Agbalagba ki i wa ni ọja ki ori ọmọ titun o wọ. Nitorina a bẹ Ijoba Gbogbo ki nwon da iru ise buburu yi duro ni arin ilu gbogbo. Mo dupẹ aye ti e gba mi.

Emi ni,
K. OLA. AKINLAWON
Ile Aloje, Idi Apẹ,
Agọ-Owu, Abẹokuta.

Ẹnyin ọmọ Igbaye, kini ero nyin?

JOWỌ gba mi laye lati bere ibere yi lowọ awọn ọmọ ilu Igbaye; ti nwon wa ni Ghana pe kinise ti a ko fi ma a gburo won ninu Iwe "Irohin Yoruba", bi awọn ọmọ Yoruba Oke-Okun gbogbo yoku ti nse?

O to o si ye ki gbogbo awọn enia ma a gbọ ohun awa ọmọ ilu Igbaye ti o wa l'Oke Okun bi a ti nse akiyesi idagbasoke ilu wa si, ki a si ma a se ipade lori re Eyiti o ba ye pe nipa isowọpọ ni a o fi se e, ki a se e,eyiti o ba si ye pe nipa kike pe Ijoba ni ki a ke pe Ijoba ki nwon se e fun wa.

Ẹ ma se jeki a fi oran ilu wa da agunla o, toripe bi a ba dake ti ara wa a ba wa dake ni o.

MOSES ADE. OJOLOWO.
P. O. Box 15,
Offinso-Kọkọtẹ Ashante,
Ghana.

Ẹnyin Onigbagbọ, ẹ la ọrọ yi ye mi?

INU mi yio dun ti ẹ ba le gba mi laye lati kesi awọn Onigbagbọ lati inu Iwe "Irohin Yoruba" "Akọmologbọn". Ki nwon ba mi se alaye aditu ọrọ kan ti mo ka ninu Eksodu ori kerin ese kerinlelogun (Exodus 4: 24).

Tani Oluwa fe lu pa ninu Mose ati Farao? Bi o ba je Farao ni, kinise ti o fi je pe aya Mose ni o fi eje ikọla ọmọ re gba Farao sile? (wo ese 26) ti o ba si se pe Mose ni, kini ese ti Mose se ti o mu iku dani?

Ẹ jowọ, ẹ ba mi yanju ọrọ na o, ẹnyin Onigbagbọ ti o ni ẹkọ ijinle ninu ọrọ Olọrun (Bibeli Mimọ). Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi, oju ko feraku o.

Evangelist M. O. Akinsanmi
(Awoko Jesu)
SW 7/4 Old Barrack Road,
Oke-Bọla, Ibadan.

EYI NI AKỌKỌ TO KORO

PHENSIC

SINU BEBA-IDAN-NDAN TO FARAHAN

Nisisiyi o le ra koro Phensic meji ti nwọn dipọ ni mimọ dada—o to lati mu u lẹkan

Nwọn nta Phensic pupọ pupọ nitoripe o daraju, o dara pupọ ju, ju aspirin nikan lọ! O ni awọn egbogi alagbara meji miran ninu ti o dara gegẹbi aspirin.

Phensic nda ẹsanri ati ara riro duro, ki o si lo o nigbakugba ti otutu tabi iba ba nfẹ se ọ. Phensic daraju, o dara pupọ ju, ju aspirin nikan lọ.

O nma ninu ọgọ pelu

PHENSIC

FUN ARA RIRO ATI IBA

O lagbaraju, o yara ṣiṣẹ ju, o si dara ju Asprin nikan lọ!

Igbadun wa ninu

Ọti Heineken's

Otutu O mọ, Ọti Heineken ko si nkan to dara julọ! Ọti Heineken dara fun ara, O kun fun igbadun ati orun didun daradara! Ọti Heineken Yio fun ọ ni alafia titi di aro ijokeji tabi jubẹ lọ!

Heineken ti Holland
O le ni ọdunrun ọdun to o ti wa

Orun didun pẹlu agbara lo so

Ọti Heineken's

di ọba gbogbo awọn ọti

ỌRỌ-OLOTU

Rikiṣi pa wọn pọ nwọn d'ọrẹ

GẸGẸBI ọrọ Oni-Psalm ti o sọ pe:—"O ti pẹ ti ọkan mi ti mba awọn ti o korira alafia gbe pẹ. Alafia ni mo nfẹ ṣugbọn nigbati mo ba sọrọ ija ni tiwọn." O ti pẹ ti awọn Ẹgbẹ Afẹnfẹre (Action Group) ti nsa agbara wọn pe ki alafia ki o le wa fun gbogbo orile-ede Naijiria, ṣugbọn nigbati nwọn ba nse eto wọnyi, ija ati ijowu ni ti awọn Ẹgbẹ Alakuko, ti awọn enia npe ni "Eni-ẹsin-Eni-ẹsin" l ma a gbe ko wọn.

RIKIṢI pa wọn pọ, nwọn di ọrẹ, ko le to ọjọ ko le to osu ti ọrẹ na yio fi baje. Ohun ti o fa ọrọ yi ni ikede ti Ogbeni Anyansi, Alaga Igbimọ Ọsiṣẹ Ẹgbẹ NEPU dapọmọ Ẹgbẹ Alakuko Ipinlẹ Ariwa ṣe ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kejidilogun osu yi pe, awọn Ẹgbẹ Alakuko ko ni yan asoju kankan lati dibo fun ni Ipinlẹ Ariwa ninu idibo ti wọn fẹ ṣe yan asoju sinu Igbimọ-Nla Apapọ Ijọba Naijiria ninu ọdun ti o mbọ yi.

ANYANSI ni idi ti awọn fi fẹẹ ṣe bẹẹ ni pe awọn nfẹ bi awọn o ti ṣe so owọ po di-pampa pelu Ẹgbẹ-Olomi (Northern People's Congress) lati bi Ẹgbẹ Afẹnifere subu ni Ipinle Ariwa nitori ẹṣẹ Ẹgbẹ Afẹnifere ti ṣe nranlẹ ni Ipinlẹ Ariwa ju ti awọn Ẹgbẹ Oselu yoku lọ. Oran yi ka won lara to bẹẹ gẹ ẹ ti nwon fi pinnu pe awon ko ni di ibo fun awọn asoju ti Ẹgbẹ NEPU tiwọn paapa ba yan. Ẹgbẹ NEPU kanna yi ni ẹka Ẹgbẹ Alakuko o.

"ANJUWỌN ko ṣe wi lejo, ija ilara ko tan boro". Awọn Ẹgbẹ Alakuko ri pe Ẹgbẹ Afenifere ngbori lowọ wọn ni nwon ṣe pamọpọ pe bi o kanran ki awọn dibo fun eka Ẹgbẹ won (Ẹgbẹ NEPU), awọn o kuku dibo fun Ẹgbẹ Olomi (NPC) ki awọn pelu Ẹgbẹ Olomi le ni agbara to lati bi Ẹgbẹ Afenifere ṣubu ni Ipinle Ariwa. Nwọn ko si wa mọ pe, eniti a ba pete-pero pe ki a da owọ rẹ delẹ ni ti Ẹgbẹ Afẹnifere, npele ni yio ma a pele si i.

AWỌN ẹmi irira Ẹgbẹ Alakuko ti a ti nso fun nyin lati bi ọsẹ merin sẹhin pe ko le jeki Ẹgbẹ Alakuko toro ni ẹ kuku nri yi. Nigbati Dokita Nnamdi Azikiwe lọ ṣe ibewo Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa laipe yi, ti gbogbo awọn onilakaye nso wipe, ọtẹ kan ni Azikiwe lọ di pelu Sardauna Sokoto. O ni iro ni nwọn npa mọ on. Ṣugbọn nisisiyi otito ko wa fi oju han'de bi?

"AṢẸNI-NṢE-ARA-RẸ" ni ọran Ẹgbẹ Alakuko, ṣe ki a ma a fi dudu pe funfun ki a ma a fi funfun pe dudu, ki a ma a pe irọ ni otito, ki a ma a pe otito ni irọ ti Azikiwe ti saba-bo na ni o wa ngbogun ti i nisisiyi ti o nda a laamu ti Ẹgbẹ Alakuko fi da si meji yi. Nipa ti Ẹgbẹ Dẹmọ Eko ti Ologbe Herbert Macaulay da silẹ lati inu ọdun 1923 nigbati nwọn dapọ mọ Ẹgbẹ Alakuko (NCNC) ni iparun de ba Ẹgbẹ Dẹmọ na l'Eko. Awọn Ẹgbẹ na pin si ọna meta ki a to tun ma gburo wọn mọ patapata ni Eko nisisiyi. Awọn Ẹgbẹ Alakuko ko ni dapọ mọ ẹgbẹ kan ki ẹgbẹ na ma di ologbe. Arun kọọli ti npa awọn akuko ko sẹhin lẹhin awọn Akuko, bẹẹni arun irọ, ilara, ijowu ati imotara-ẹninikan ti mba Ẹgbẹ Alakuko ja ko sẹhin lehin wọn.

BI o kanran ki nwọn fi ma a lọ siwaju, ajorẹhin ni Ẹgbẹ Alakuko njo lojojumọ. Eyi wa ninu alaye ti Dokita Mbadiwe, Olori Atunto Ẹgbẹ Alakuko ṣe ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kejidilogun osu yi nigbati o mba awọn ipade Ẹgbẹ Atunto na sọrọ lori idi ti Dokita Azikiwe fi ni lati fi aye re silẹ gẹgẹbi Olori Ẹgbẹ Alakuko ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun....O ni Azikiwe nkigbe, alafia, alafia, alafia nigbati ko si alafia ninu Ẹgbẹ Alakuko.

MBADIWE ni ti kini kan ba ti kan Azikiwe kẹrẹ, o ti di ti gbogbo ọmọ Ẹgbẹ Alakuko niyen, o ni bi ori ba nfo Azikiwe a fi ki gbogbo ọmọ Ẹgbẹ Alakuko ma a lọ ra ogun ẹsanri, ki gbogbo wọn ma a mu u. O ni eyi mu ki gbogbo awọn onilakaye fi ma a ro pe awon ko ni ogbọn kan lati lo fun oran iselu ju ogbọn Azikiwe nikan lọ. Nitorina o tọ ki awọn fi han Azikiwe pe, ti o ba nfi oju alaimọkan wo gbogbo ọmọ Ẹgbẹ Alakuko ti o nse olori fun, awọn ki ise alaimokan. Bi Azikiwe ba fi aye Olori Ẹgbẹ yi silẹ, Ẹgbẹ Alakuko yio si ni i lọsiwaju ju bayi lọ.

OJU aiye re o. Aṣa nfo fẹ ẹ! Awodi nfo fẹ ẹ! rikiṣi ko jẹ ki adiẹ o fo fẹ ẹ!

Ọlawọyin di ọkan ninu Igbimọ Alamojuto eto owo Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun

IBADAN.

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kejilelogun osu yi ni Ijọba ṣe ikede ni Ibadan pe nwọn ti yan awọn Ogbeni J. S. Ọlawọyin, Akọweagba Eka Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) Ipinlẹ Ariwa ti iṣe Asoju ilu Offa ninu Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ariwa ati Ogbeni E. A. Motayọ, Loya kan l'Eko, si Igbimọ Alamojuto Eto Owo Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun lati ọjọ kẹwa osu yi.

Dab on Sloan's-

IRORA SI LỌ PATAPATA

Lẹṣẹkẹṣẹ ni "SLOAN'S LINIMENT" ti npa irora! Irora Lakuregbe, aragigan, fifi bikan ro lana, irora orikerike ara.....ẹ̀a ti gbọn "Sloan's Liniment" rẹ ibiti o ba ndun ẹ—ko si ni i si ara-didun ati irora fun ẹ mọ! Ma a ra igo Sloan's Liniment" kọọkan ti'ra nigbagbogbo.

Bi o ba nfẹ egbogi ipara ti o ngmu ara jọlọ ni titun, egbogi tworan "Soan's Balm" ti o lagbara ti o ni nyara ṣiṣẹ. Eyiti nwọn fi iru elo-egbogi kanna bi ti "Liniment" ṣe, "Sloan's Balm" npa irora lọgan. Nkan iyanu ni fun otutu-ori pelu. Dan "Sloan's Balm" atura wo lonii.

Ilera mi dara-dara

L'ẹrọ

Andrews

Ṣe ara re silẹ, o si gbe kankan nigbati o ba ji? Bi ko ba jẹ bẹẹ, o le jẹ pe awọn oolọ inu nlọra. Aseko yen gan an ni igbati o ni lati lo Andrews! Nitorina:—

(1) Gbe pangolo Andrews re jade.
(2) Bu ẹkun ṣibi kekere meji sinu omi ki o ru u po kiakia.
(3) Mu u bi o ba ti nru soke.

Hiho ati didun l'ẹnu Andrews a ma a tutu ẹnu ati ahan. Nigbana ni gbogbo inu o wa joko pẹṣẹ a si le gbogbo irora inu lọ. Lakotan, Andrews ngmu ki ẹdọki ṣiṣẹ gbadun o si ngmu igbonsẹ wa, yio si ṣọ inu di ọtun.

Agolo Tolọmọde—3/6d.
Agolo Imudani—2/6d.
Agolo Kalowo—1/6d

OJOJUMỌ NI ỌJỌ AAPỌN

Maṣe jẹki aiṣe-deede gba agbara re. Jẹki inu re mọ, iwọ yio si ni ilera ati agbara! Mu Andrews ti o nho suṣu laro—Eyi ni ọna taara lati fi fọ inu nu! Andrews yio mu aiṣe deede ara re kuro yio si fun e ni ilera ti o ni igbadun. PELU IFONU-NU!

K.369.5

Ijọba mba Sunday Shotayọ s'ẹjọ lori iwe ori're ti o ko ta laisanwo rẹ

IBADAN.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣẹ ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni awọn ọlọpa mu Sunday Shotayọ ọmọ ọgbọn ọdun wa siwaju Ọgbẹni R. W. Rhodes-Vivors, Adajọ Agba Kotu Kekere Onireke Ibadan fun ẹsun pe o ji idiiwe ori're mẹjọ ti iṣẹ ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun gbe ta, ko si ko owo rẹ fun Ijọba na, owo gbogbo awọn iwe na ti o ta ti ko si ko owo rẹ fun Ijọba na mọ si jẹ ogun pọnun (£20).

Nigbati ọdaran na ni on ko jẹbi ọran na ni adajọ na ba yẹ ọjọ gbigbọ ẹjọ rẹ si ọjọ kejila oṣu kẹsan ọdun yi, o si gba iduro fun un pe ki o fi adọta pọnun (£50) dogo ati ohun iduro onlye owo na.

Awọn Oniwe Irohin Naijiria meji nrin Ilẹ Jamani wo kakiri

LAIPẸ yi ni awọn oniwe Irohin Naijiria meji Ọgbẹni Gabriel Idigo, Olotu Iwe Irohin **Daily Times** ti Ipinlẹ Ila-Orun Naijiria ati Ọgbẹni M. A. O. Pearse, Gbakeji Olotu Iwe Irohin **Daily Service** l'Eko ti awọn Alakoso Ile Iṣẹ Itẹwe "German Federal Press" ati Ile-Iṣẹ ti nṣẹnu fun Ijọba (Information Office) fi iwe pe ati wa se ibẹwo Ilu Jamani de si ilu Munich lati rin irin ibẹwo ọsẹ meta yika Ilu Apapo Ijọba Jamani (Federal Republic of Germany).

Awọn ilu Jamani ti o wa ninu eto ibẹwo na ni Stuttgart, Bayreuth, Frankfurt, Mannheim, Heidelberg, Bonn, Cologne, Duesseldorf, adugbo Ilu Ruhr, Kassel, Berlin, Bremen ati Hamburg. Awọn oniwe Irohin na yio se ibẹwo awọn Ile-ẹrọ iṣẹ-owo, awọn ile atijo ti o mu itan dani, ile-ẹkọṣẹ ati ti Iṣela, nwọn yio si ba awọn enia pataki-pataki ti o wa nibe sọrọ pelu. Ni ojo Eti ti iṣẹ ojọ kejo oṣu kejo ọdun yi ni nwon yio ba oko-ofurufu pada de si Eko.

Awọn ole fọ'le iṣẹ Daily Service ni Ijẹbu-Ode

IJẸBU-ODE.

NI ọjọ Aiku ti iṣẹ ogunjọ oṣu yi ni awọn ole lọ fọ ile-iṣẹ Iwe Irohin **Daily Service** ni 139 Folagbade Street, Ijẹbu-Ode, awọn ọlọsa na ba gbogbo ọwọ ilẹkun ati oju kọkọrọ ilẹkun na jẹ pupọ ṣugbọn nwọn ko le ji nkankan lọ nibẹ. Nwọn koi ti mo awọn ole ti o ṣiṣẹ na ṣugbọn awọn ọlọpa si nwadi oran na.

Karimu Amọo sọmọlorukọ

IWO.

NI ọjọ Eti ti iṣẹ ọjọ keji oṣu karun ọdun yi ni Olọrun fi ọmobirin kan ta Ogbẹni Karimu Amọo ati iyawo rẹ Rabiatu Arikẹ lọrẹ, nwọn si sọ ọmọ na ni orukọ ni ọjọ kejo ti nwọn bi i lọna ẹsin Musulumi, nwọn si sọ o ni Suliya Ọmọlabakẹ. Awọn obi ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣeyẹ ọjọ na lọrun.

Diẹ ninu awọn alabaṣeyẹ na ni awọn Ogbẹni Tiamiyu Arẹmu, Mudaṣiru, Salawu Ogunwawo, Salawu, Alatẹdẹ ati awọn Iyaafin Awawu, Sinatu ati iya Yindia. Ki Olọrun da ọmọ na si ki O fi ire kari o.

O npese agbara ọla silẹ

Orun asunwora ti ko ba mu iyonu dani nso gbogbo agbara ati okun-inu di ọtun. Agbara titun ati okun-inu a si wa fun ojo keji. Eyi ni o mu ki ogunlogo awon olomọ-lẹbi fi ma a mu Ovaltine ki nwọn to sun lale, agabara titun-eje-se rẹ a ma a mu ara sile a si jẹki enia le sun asunwora gegebi o ti ye, wa a ji pẹm ara-yoya ati pelu ẹmi akotun ati ara lile. Ovaltine olokiki ti gbogbo aiye ti mọ je onje—mimu aladun ti o ntun eje se.

OVALTINE



Ara lile ti o nfun ni ko lẹgbẹ

O NWO EGBO SAN O NGMU AWỌ ARA JỌLỌ

Mentholatum a fun e ni Itura were-were Bi o ba ni egbo tabi awo ara gbigbe tabi isaka tabi irewesi sa fi egbogi ipara Mentholatum pa ibẹ. Ipara ti o dara julo ni.

ṢA A MA A FI PA A

-NTURA
-NGMU ARA DẸ
-NGWO AILERA SAN

Itura Mentholatum dabi igbati atogun nfẹ lu enia lasiko ooru ọsan ni, o si ngwo ailera san, a jẹki awo ara re se mulomulo ki o si ma a dan ati ki o dasaka. Lo egbogi ipara Mentholatum fun gbogbo Inira Awo-ara. Ba bẹ tabi apolo re kan loni.

SERE FUN MEN-THO-LAY-TUM GAN AN

MENTHOLATUM

Awọn ọgbọnyo na ti o nṣe ni The Mentholatum Co. Ltd. (Est. 1889) Slough, England.

Omugo l'arun Oba Ilagida

EBA L'EWU OBA ALONJE MA-LOWO

GEGEBI orin-owe fi egun kan ti nwon npe ni Kolorata nko ni pke-ogun, ni iju fbarapa, o korin na bayi pe:—"Bi o ka ri engmo ri Igboera ni o ka de, sanmuyanmun ga lo enia, esinsin ga t'esin". A se engmo nlanla mbe ni ilu ti Gongosu ati awon elegbe re wo yi.... Lati igbati nwon ti wo ilu ni nwon ti beresi ri ukan iyanu, ekini ninu re ni wipe ihoho ni tomode tagba ilu na nrin kakiri bi ewure, ekeji ni pe nigbati nwon ya si inu buka kan lati ra onje je, nwon fun won ni onje sugbon oloja na ko gba owo lowo won.

Nigbati nwon jeun tan ti nwon kuro nibe, nwon pade okunrin kan loju ona, nwon si bere lowo okunrin na pe, dakun, ore wa, nibo ni ile Oba ilu yi gbe wa awon fe lati jo ki i ? okunrin na si mu won lo si ibe. Bi nwon ti yo si enu iloro ile na ni nwon ti ri oba na lokankan ti o gunwa larin apere, ikoko ati isasun onje ti o to yika ara, nwon din eran adie o kun inu apere kan, eran obuko dindin kun inu ikoko kan, isasun eran agutan, ti ewure ati ti elede tun wa nibe pelu, o to won yika, o si joko larin won, bi o ti nfi owo otun ya itan adie je ni o tun nfi owo osi ju edo obuko si paari ereke keji.

Titi ti awon alejo yi fi rin de odo re ko siri-pake wo won afi igbati o gbo ti nwon ki i pe "Kabiyesi o EBA L'EWU, OBA ALONJE-MA-LOWO ni o to o gbe ori re soke firi lojiji, o ni, "enyin tani wonyi, nibo ni e ti wa, nibo ni e nlo, ise kini e nse, kini e wa wa si ilu wa nihin tabi ebi npa nyin ni? Gongosu si fi owe da a lohun bayi pe "Kabiyesi, bun mi ni isu je, ki i siwaju ku u se", o ni on ko le yara ma a so fun Oba pe ebi npa awon nitoto afi bi on ba se alaye eniti awon je, o si se alaye fun Oba na pe, ahoro ilu Ajangoloto ni awon ti mbo, awon si nfe lo na oja "Were ni ilu Ilagida, alagbe ilu ati ijo ni awon, awon ko si mo pe ilu kan bi eleyi tun wa ni irona fun awon lati kan ki awon to de ibe.

Nigbati Oba na gbo bayi tan, o dide naro kia, o da owo mejeji te ibadi, o beresi wo yika, nigbana ni awon arinrin-ajo yi wa ri arisa re pe, ko si aso miran lara re ju sokoto pata (knicker) ti o wo lo, pata na ko wo idi re dada, nse ni o ha a gidagida, o fun tin-in-tin-in ko a gun de isale polotan re, enia gungun ti o sigbonie ni, o yokun o ri korobojo, ori re kere ko ju odu-agbon lo, eyinju re si yo sode dada fun isanra, iwon iba irun herehere ti o pa ki ni arin ori re ti kiranje fun aiko fi ooya ya a.

Nigbati nwon tun fi enu ko orin na jade ti Oba na gbo itumo re, nse ni o fo jade larin awon onje ti o to yika ara, o dun-un-gun gbe e! o se ho o o bi egun ti o foju diwon gegebi Oba na ti se wa si tan, o beresi fi ibi korin bayi pe:—

"Eba l'ewu, Bi'nu ba ti kun eran buse Eba l'ewu!
Bi'nu ba ti kun eran buse, Eba l'ewu.
Bi'nu ba ti kan eran buse
Eba l'ewu.

Nigbati nwon tun fi enu ko orin na jade ti Oba na gbo itumo re, nse ni o fo jade larin awon onje ti o to yika ara, o dun-un-gun gbe e! o se ho o o bi egun

Lati owo J. Olurebi Williams, Mushin

O si fi owe da Gongosu lohun bayi pe: "Kini mbe nile osu ti ko si nile ojo". Kini wa ni ilu Omugo l'arun Oba Ilagida ti e ko le ri ni ilu on **Eba l'ewu Oba Alonje-ma-lowo?** bi e ba nfe je iyan on yio gun un fun nyin, bi e ba nfe oka amala on yio ro o fun nyin, bi e ba nfe je eran on le fun nyin leran je titi ti ehin nyin yio fi ka, o ni awon ara ilu on ko si mo ohun ti nwon npe ni owo tabi aso, ihoho-ibimbi ni gbogbo awon wa, onje nikan ni awon mo ni oro enia l'aiye yi. Laiduro gbo oro kan lenu Gongosu mo, o pase pe ki nwon gbe pakata iyan nla merin, ikoko obe eran merin, eko nfo ti nwon da oyin igan si igba-ademu merin fun won pe ki nwon fi pa orungbe.

Ni wara nsesa ti nwon ti ko onje wonyi sile ni Agunla ti bo ewu re sile, o de okun sokoto re, o si mu obe olukondo ti o fi nti egun-gun-eran je si owo osi re ki nwon to beresi jeun, nigbati nwon beresi jeun ni Latigo bere lowo Agunla pe, bawo ni ti olukondo ti o yo dani ti je? o si da a lohun pe, boya enikan le fe di on lowo nigbati awon ba beresi jeun ni.

Nigbati nwon jeun tan ti nwon pada de odo Oba. Oba ni ki nwon wa se ere ti nwon nse na ...fun on, Latigo si beresi fi ilu ki "Eba l'ewu", o ki i titi ko si mo iru orin ti on le fi gbe kiki na lese, sugbon nigba-lemeta ki o to beresi si i jo, o f'owo gbe ikun re soke, o beresi rababa kakiri, o si njo mukemuke pelu erin idunnu ni enu re, lesekese gbogbo awon enia re ati awon Ijoye re tun mba a jo pelu.

Nigbati ijo yi kara tan, Oba na gbe apere eran-adie ti nwon fi ororo din kan jade, o fi owo mejeji bu eran-adie, o nfi itan-adie kookan ha awon onilu na lenu ati gbogbo awon ti o mba a jo pelu, lehin eyi, o tun ko awon onilu na lehin pelu awon ti nwon mba a jo, nwon beresi jo lati ile de ile, lati odede de odede ati lati kaa de basa, gbogbo ilu gbojikan fun ijo ati ilu.

Gbogbo awon enia ti nwon nlo jo ba nile ko ni nkan miran ti nwon le fi ye won si ju onje ati eran lo. Edidare jeran titi o nyagbe orin, mern ka ninu ehin Agunla, Latigo jeran titi erigi re wa papo, ko tun le jeran mo, Gongosu ko roju fi gbogbo ara jeran nitoripe on ni o ndarin nigbati awon yoku di olokunrin on ni o si ntoju won.

GONGOSU DA IRUNGBON SI

Nigbati Gongosu ri i pe awon ko ri owo gba fun odidi ojo medogun ti awon ti nsire fun won ni ilu na, o dagbere fun Oba pe awon yio sise siwaju kuro nibe lo si ibomiran ni ojo-miran, (iyen ni pe ni ojo keji) Oba na si gba fun won, o ni ki nwon lo dagbere fun awon Ijoye on pelu. Nigbati nwon lo dagbere fun Balogun, o fi odidi agbo kan ta won lore nigbati nwon dagbere fun Otun, o fun won ni agbo kan, nwon dagbere fun osi, on na tun fun won ni agbo kan, nigbati nwon si tun lo dagbere fun Iyalode ilu, on na tun fun won ni odidi agbo ka pe ki nwon ma a pa won je ni okookan nigbati nwon ba nlo ni ikin-ajo.

Lehin ti nwon ti dagbere fun gbogbo enia tan ti nwon si ko awon eran agbo won de ile ibiti Oba fi won wo si, nwon so awon agbo mererin wonyi mo abe atibaba ti nwon ta fun won lati ma a sere labe ibouji re pe, bi o ba di ojo keji ki awon ma a da won lo. Nigbati o di oru oganjo ti arare ninu omi ti o wa ninu koto ti o fe fi we ni owuro ojo kan, o ri i pe, irungbon didasi ye on ju oboro ereke lo, o kuku yun un nu, o da a si.

DANA-DANA FA GONGOSU NI 'RUNGBON

Ili ile ojo keji ti mo fisan, nwon ran Agunla pe ki o lo da eko gbigbona wa, ki o gba akara, ki o si gba yanko (adi) ti awon yio tu si eko na ki awon to mu u nitori ki jedijedi ma a ba a je se won. Latigo ti gba-gbe pe nwon ki i na owo ni ilu na o nawo owo si iya eleko titi ko gba a lowo re, sugbon iya na ro eko gbigbona kun inu koto nla na fun un.

O tun de odo iya alakara, o nawo owo si i iya na ko tile mo owo na si kini kan, ko si gba a yewo lowo re, o yan akara kun igbaje (pakata kekere) o gbe e fun un, nigbati o de odo iya-aladi, o ni, "iwo iya oniyanko yi o, ngo ma a wo o boya omugo tire yio po ju ti awon ara yoku re lo gba owo yi, mo fe si konjo yanko kan?"

(WO OJU EWE KEJO)

'Tani o si apoti ipamo oti-tutu'

Sammy Sparkle ni 'Emi ni'

... Asiko STAR' to

OSTERMILK

njeki omo-owo

lagbara! lokun ninu!

nitelorun!

IYA ko le fun omo-owo l'onje mo, opelope agbaaiye wara Ostermilk. Ostermilk, wara ti o dara lonje. o je mu ki omo-owo re lagbara ki o si ni ilelo-run pelu. O ni afikun onje okun-inu pupo (extra Vitamin D ..... extra iron) pelu. Mase daamu Ostermilk ma a nwa ni akotun peju wara lasan lo... nitori nwon nde agolo re pa daada. Sa ti fi omi po Ostermilk... fun omo-owo nu .. wa a si ri omo na ti yio ma a rerin muse-muse!

OSTERMILK

MADE BY GLAXO LABORATORIES LTD., GREENFORD, ENGLAND

Agents: ACCRA: F. E. HARDING & CO. (GHANA) LTD., HIGH STREET. LAGOS: F. E. HARDING & CO. LTD., 38 COMMERCIAL AVENUE, YABA

Alimi Oyewale di baba'beji

Were enia ni i sọ pe iru on ko si laiye

Peter A. Oyinloye ni

Lati ọwọ B. A. Alhaji Ashiru Shaki, Niamey Niger F.W.A.

Eniti o mọ?...

mọ wipe Taya mọto MICHELIN ni o darajulọ fun ilẹ NAIJIRIA

MICHELIN

SCOA - Awọn alagbata ni - CFAO

Owe ilẹ Yoruba

OWE ILE YORUBA
Lati owo J. Olurebi Williams Mushin.

1. Ab'ẹda lo le b'ala-ṣeṣu gbele
2. Amunara soromu, bi eni je majele san lori, were ni ku awo.
3. Ero Mẹkka to ki ku-ewu, opo ebi ko to ti danadana Larubawa.
4. Bi Sango ko ba tete p'oje, oje ni yio pa Sango.
5. Tete-popo ab'onde lorun, olukaluku abitire lara.
6. Olopipi on asa lo le b'asa rin, Elebure lo le b'ebolo gbe.
7. Ojo ku gi iri, otoṣi ni ki Sango wo ile oloro ko so aara si, bi o ba se wipe bi inu ti mbi otoṣi be e ni inu mbi Sango, gbogbo ile oloro ni iba ti parun.
8. Pakiti k'oran ajo, gbaguda ko'le ana ko lo, okobo ko'se ana panun.
9. E ma jek'o baje, enu ni aberẹ fi ntun aṣo se.
10. Arun ti o nse obo ko se igun, igun pari, obo pa'di.
11. Eyiti o nse epo ko se ora, epo nfe e yo, ora nfe e sun.
12. Iya nu mi nidi nu? omo, bo ti nse o lo nse mi.
13. Aigbon lo nse ogboja, nwon ni iya re ku, o ni on darodaro, tani o ni lati de Awoyade?
14. Bi aye ba gba Ekuluodan, a fe nipon laiya bi Ira, bi olowo ba jeun yo tan a ma a wa iku kiri
15. E yun gogo nu fun odawe, e roju yun oko nu fun onilara.
16. Bi a ba de aso fun alaso, a ma a to alaso hun.
17. Ipako ko gbo suti, eni ba wehin lo nr'egbin.
18. Oju ti o ti ri okun ko tun beru osa mo, awa ko je ri elewu ta kiji, afi eniti o ba wo irin l'aso
19. Kinun ki i to ole, afi gbau kumo lehin orun.
20. Omo-olomo ni i je ariku-ma-sa, ojo-pa-siwere-ma-ya.
21. Onile re'le, e ni onde sa, onde ko sa ile baba re lo gba lo.

Awọn Olopa mu odaran ti nwọn ti nwa lati odun keje wa si kotu

ABEOKUTA.

NI ojo 'Ru ti ise ojo kerindilogun osu yi ni awọn olopa mu esun Jimo Sanni, ogbologbo elewon kan, eni ogoji odun wa siwaju Adajo "Ake Grade A Court" fun esun ole: pe o ji Bisiriyu Akinbode, Asoju awon Oyinbo Elepo Moto ti o wa ni Abule Ilugun nj korodomu epo moto kan ati ekun galloonu epo moto mejila aropo iye owo re je ponun mefa sile medogun ati kobo mejo (£6. 15. 8d.).

Alfred Gbolagbade, Oga Olopa'nu ti o nse Agbejoro Ijoba so fun Adajo na pe odaran na fo sobu Akinbode ni alẹ ojo kewa osu keji odun 1952, o si ji korodomu epo ati awon galloonu epo moto mejila na gbe lo ta. Sunday Oluwole ti o ta epo moto na fun ni on ni odaran na ta gbogbo galloonu epo mejila na fun. O ni nigbati on ko fe lati ra a lowo re ni Jimoh Adebeshin ti o tele e wa si odo on ni o ro on pe ki on ra a ni on ba fi ra a.

Ki nwon to ye gbigbo ejo re si igbamiran ni awon olopa ti fi han Adajo ninu alaye won pe ogbologbo elewon ni odaran na nitoripe ninu odun 1952 nigbati Olopa'nu Sajenti James Kodaolu mu u fun esun pe o fole ti nwon si fi sekesẹke si i lowo, o si salo lati bi odun keje sehin ki nwon to tun sese ri i mu yi.

Bi nwon ba ti pari ejo re si, e o ma a gbo o.

Arun Oba Ilagida

Lati oju ewe karun

Iya oniyanko wo o titi, o ni, iwo ma kuku go lagoju o, o nfe ba eewo ilu yi je ni? ko gba owo na lowo re o ro yanko kun ata (pere epo) nla kan o gbe e fun un. Nigbati Agunla ru gbogbo nkan wonyi dele, o rohin fun awon ara re, sugbon on paapa ni nwon dalebi fun iwa omugo, nwon fi owe so fun un pe: "Bi enia ba de ilu adete nse ni i di ikuku rin, ohun ti awon ara ilu ba nse ni a mba won se".

Nigbati nwon mu eko iwon iba ti nwon le mu, ti nwon je akara iba ti nwon le je ti nwon yo tan ni nwon ba da eran won siwaju ti awon na si ntele won lo. Bi nwon ti nlo ni Latigo nfi ilu ki Gongosu ti nwon si nfi orin won se idaraya lo loju ona. Agunla nikan ni nwon di gbogbo eru won le lori, nigbati o beresi kigbe wipe orun nwo on, nwon ni ki o ma a fa itanadle kookan yo ki o ma a je e lajerin. Agunla si feran eran-jije ju ikoriko lo.

Nwon koi ti lo jinna pupo larin aginju na ti okunrin onihoho kan fi yo si won pelu obe ti o mu, ti o si nko mana kan, o sunmo Gongosu, o fa a ni irungbon tototo, o ni "Gongosu, Gongosu, Gongosu, igbati iwo yinbon paupau ni Alonje lana iwo ko mo pe ibon na npaniyan, iwo abinu-gbon-selele yi?" Nigbati Edidare ri ohun ti o sele yi, o figbeta, o ni, "e gba wa o, awon ole yi tun de o!"

Danadana na si da a lohun, o ni "E he o! Edidare, awa ko ba iwo wi, Gongosu oninu-gbon selele yi ni awa ba wi, ko mo pe ibon npaniyan, jeki nfi igbada (obe) yi ko ifun le jade, ko mo pe ibon npaniyan! Nigbati Gongosu woye pe, dajudaju, Dana-dana na fe gba on lobe nikun, o ni, Ai, abilii ni e ma nfa lese yi, ngo ma tun yinbon fun nyin? Lesekese o tun fa ibon ana yo o si yin in gbau! awon ole na si tun salo.

Eyi ni aworan die ninu awon odaran merindinladorun ti Ijoba mba se ejo-apania ija-igboro ti nwon ja lehin iku Alhaji Adelabu. Ni ojo Aje ti ise ojo kokanlelogun osu yi ni nwon bere ejo won ni Kotu Ganran Ibadan.

Kinişe ti awọn Ijọ Onigbagbọ kan ṣe nję "Onitębọmi"

OLOTU, ẹ jọwọ gba mi laye lati bere ọrọ kekere yi lowọ awọn ọjogbon Onigbagbọ lati la ọro na ye mi. Ibere mi na ni pe:—Nigbati o je pe gbogbo awọn Onigbagbọ ni o nse itębọmi, sugbon nwọn ki i pe gbogbo Onigbagbọ ni Ijọ Onitębọmi. Kini iyato ti o wa larin awọn Ijọ Onitębọmi yi ati awọn Ijọ Kristieni miran?

Olotu, mo dupẹ aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
DAVID OJO.

Ghana.

★ ★ ★

IDAHUN SI IBERE OKE YI

Ki awọn onkawe **"Irohin Yoruba"** ma ba a ma a ta ataba lori idahun ibere yi, mo ri i pe o to, o si ye ki nkuku da onibere na lohun jekan ki a ma ba e fi akoko aofo. Sugbon ti a ba si ri ninu awọn onkawe wa ti o fodi si idahun ti ma a fun onibere na yi ki o ko o wa ma a si te e jade, sugbon ti a ba tun ri eniti o tun dahun ti idahun re ko ba yato si t'emi ti mo dahun yi, a ko ni te e jade.

Idahun mi si ibere na ni pe—**Awọn Ijọ ti nwọn nję Ijọ Onitębọmi ti gbogbo enia si mọ wọn bę e jakejado agbaiye ni awọn Ijọ ti o tęle apere Johanu Baptisti ti o nse baptisimu fronupiwada ni odo Jọdani, on na ni o si ri Jesu bọ'mi, nitorina ni awọn Ijọ se pinnu pe bi a ti se ri Jesu bọ'mi lati owọ Johanu Baptisti ni awọn ma a se saami fun gbogbo eniti o ba fe gbagbọ ninu Ijọ awọn. Idi eyi ni nwon fi nje Ijọ Onitębọmi "Baptist Church". Ẹ wo Matteu ori 3 ese 13-17. Tabi ki e ka a lati ese kini de ipari, e o ri alaye na dada nibe.**

Sugbon nisisiyi opolopọ ninu awọn Ijọ Onitębọmi yi ni nwon gbe kanga ti ko mu enia tan sinu Sọọsi wọn ti nwon si nse itębọmi ninu re. Awọn ti odo kekere ti ko le gbe enia lọ ko ba si janna si Sọọsi won, nwọn si nlọ se itębọmi lodo.

Idi ti awọn Sọọsi yoku ko se nję Ijọ Onitębọmi nipe kotopo-kekere kan ni nwọn nro omi si ti nwọn si ngbe s'ori ipeku ti nwọn ti ya si mimọ ninu Sọọsi ti nwọn si nya omi inu re si mimọ ti Alufa-Ijọ si ngwọn si awọn ti o ba fe sami lori ni oruko Baba, ti Omọ ati ti Emi-Mimọ pelu ami agbelebu si aiya wọn (Awọn Ijọ wọnyi ki i ri enia bọ-omi). Iyato ti o wa larin awọn Ijọ Onitębọmi yato si awọn Ijọ yoku ni mo so yi o,

Emi ni tinyin nitoto,
S. M. ADEMUYIWA,
(Olotu Irohin Yoruba),
Eko.

A nfẹ iranlọwọ ni ilu Irawọ

IDERA ati igbadun wa ninu gbogbo eto ti Ijọba ti Iwọ-Orun nse nigbati Egbe Afenifere ti bere. Ni ilu Irawọ gbogbo wa lokunrin ati lobirin ti Egbe Afenifẹrere ni a nse a si bura lati ma a se e lọ titi nitoripe Ijọba re dara pupọ fun gbogbo wa.

A bę Ijọba Iwọ-Orun lati tubọ ba wa mojuto oran ilu wa nitoripe Igbimọ Ijoba Ibile wa ko ran wa lowọ rara. Ona ti o wọ ilu yi ko dara rara. Odo nla kan si wa ti ko jęki oko le wọnu ilu na. Awọn ara ilu yi ko nfi oju kan oko rara bi nwon ko ba wa si ilu keji ti o sunmọ o bi ibuso mefa.

A sa agbara titi lori odo na nipa dida owo miran lerin meta lehin owo-ori, sugbon agbara wa ko ka odo na. O wa dabi ki a ko adie sinu ago ki nwọn ma rọna jade.

Ni ilu yi ile ẹjọ kekere kan na ni a ni, ọdọdun ni a si ndawo ori o. Ẹ jọwọ, e tubọ ran wa lowọ o. Olotu mo dupẹ pupọ fun aye ti o gba mi.

Emi ni,
LADE OJE.
Irawọ-Shaki.

A bę Ijọba Ipinlę Ariwa fun amojuto ilu Ajaşşẹpo

GADA ilu Ajaşşẹpo ti o wa ni ona Oro wulo pupọ fun awa omọ ilẹ Igbomina. Bi a ba ti kuro ni ilu Offa tan ko si eniti ki i gba ori gada na lọ si ilu re. Sugbon gada na ko dara to: nitoripe awọn moto ko le rin lori re rara.

A bę Ijọba Ipinlẹ Ariwa ki nwọn ba wa tun gada na se dada de aye ti awọn moto yio ma a fi gba ori re ni irọrun, ki nwọn si tun ba wa kọ ile-iwosan ati ile-itọju awọn aboyun ati awọn abiyamọ. Oniruru aisan ni o nyọ awọn ara ilu lenu ti o si je wipe afri ile-iwosan gbe wọn lọ ni itosi tete mu ki nwọn ku. Nwọn a ma a gbe awọn alaisan miran lọ si Oshogbo tabi wa si Eko fun itọju lati Ajaşşẹpo. ki nwọn to de ibe, omiran a ti ku.

Awa ara Ajaşşẹpo ki i fi owo-ori jafara lati san: nitorina, ẹ jọwọ ẹ gba wa kalẹ o. Inu wa yio dun ti Ijọba na ba le ba wa se wọn laseko fun anfani gbogbo wa.

Emi ni,
SALAMI AROWOŞAFẸ.
(Ajaşşẹpo)
Pedro St., Lagos.

Imọran fun Alabojuto Ile-Iwe

PATAKI ni o je fun omọdekunrin ati omọdebirin lati mọ iwe ka ati lati mọ o ko dada. Nitorina ni awọn ara ilu Naijiria ati awọn ara ilu miran se feran lati maa ran awọn omọ won lọ si ile-iwe fun eko. Sugbon o seni laanu lati ma a ri i ka ninu awọn iwe irohin pe omiran ninu awọn olukọkunrin a ma a ni idapọ aito pelu awọn omọbirin ti nwọn fun won ko.

A gbọ pe irufe iwa ibaje bayi sele lenuloloyi ni Ile-iwe "The United African Methodist Church School" l'Eko larin Alabojuto Ile-iwe na ati omọ Alufa Sọọsi na kan. A gbọ wipe Alagba-Ijo (Elder) E. A. A. Williams dide si ọro na. Kini Alamojuto Agba Ile-Iwe (Chief Education Officer) se si i?

Ti oluko ile-iwe tabi Alamojuto ile-iwe kan ba fe lati ni iyawo, ki o ni i lona eto, ki o mase ba igbesi-aiye omo ile-iwe je. Ki Olori awọn alamojuto ile-iwe (Chief Education Officer) mase gba irufe eni bę e laye rara.

"IGMAN".
Eko.

Ohun Orin ti o le mu inu rẹ dun

PHILIPS

'West African' RECORDS

Awọn ti o nta a ni.....
Badejo Stores, 5, Olorogun Street, Lagos.
Dayo Development Co., 161, Victoria St., Lagos.
Josey Ola Fajimolu & Bros. 21, Balogun Street West, Lagos.
Nwosu Brothers Stores, 24, Asa Road, Aba.

PHILIPS (WA) LTD., P.M.B. 2023, LAGOS

'ASPRO' da irora mi duro

mo si bori ninu ere idije na!

Nwon yan mi fun abule wa lati lo ba won gba bolu ala-fẹ-gba, sugbon ni ojo ere na yi gan an, mo saban; mo ni esanri ti o banilera,

Ogagun wa ni, "Bi o ba pelu wa ja ni a o le fi segun" Fi ohun mimu ti o gbona lo kero "ASPRO" meji.

Awon koro "ASPRO" wonyen sise kia-kia! Irora mi ti lo laseko ti a bere si sere—bola ti mo gbe wole awon abanidije ni awon ẹgbẹ ebere wa fi bori won!

"ASPRO" le ran e lowọ, pelu! Nigbamiran ti otuta tabi esanri ba nse e, fi "ASPRO" ogan ti o nyara ṣiṣe, ti o lagbara ti ko si ni pa okan re tabi apoluku re lara da a duro. Bere fun awon koro ASPRO ni sobu—ki o si jeki "ASPRO" ma a wa larọwọto re nile nigbakugba.

ASPRO A FUN Ẹ LAGBARA

Lori Irora ati Otutu

All trade enquiries to: E. E. HARDING & CO. LTD., LAGOS & ACCRA

Awọn ọmọ mẹjọ mu ogun aran

Ọkan ku, ọkan daku, meji di-eti, mẹrin nṣaisan

IBADAN.

NI ọjọ Iṣegun ti ise ọjọ ṣẹdogun ọṣu yi ni Ogbẹni Ade. Obe, Gbakeji Oga awọn ti nwo arun eran (Veterinary Assistant) fun awọn ọmọ rẹ mejọ ni oogun ti nwọn pe ni "Oogun aran" (worm expeller) mu. Lehin wakati die ti awọn ọmọ na ti mu "oogun" na tan ni okan ninu wọn ti fo sanlẹ ti o ku, awọn meji ya aditi gbọnin-gbọnin, okan daku fun ọjọ merin, awọn mẹrin yoku wa ni idubulẹ alsan inu-rirun ti nwọn ko le jẹun. Baba awọn omọ na so fun asoju awon Iwe wa pe lowo apoogun (Chemist) ni Ibadan ni on gbe ti ra "oogun" na.

Omọlọla Makinde, omobirin olọdun mẹfa ni omọ na ti o ku. Ni Ile-iwosan "University College Hospital" ni o ti ṣe (ashaasomọ n'o je fun Ose). Olayinka Obe, omobirin ọdun mẹwa ni omọ ti o daku. Ni Ile-iwosan Ariworiya ni awọn gbe e lọ fun itọju, ni Oke Ado.

Ohun ti o ṣẹlẹ yi ya awọn olopa lẹnu pupọ paapa baba awọn omọ na, ti o so fun okan ninu awọn asoju Iwe Irohin wa pe on ko ri iru̩fẹ ohun ti o ṣẹlẹ yi ri. O ni gbogbo ile on ni o ti daru. O ni ẹsẹkẹsẹ ti nkan yi ti ṣẹlẹ ni on ti fi moto ayokẹlẹ ko awọn omọ na lọ si ile-iwosan. O ni omọ aburo aya on ni o bi Omọlọla ti on so di omo on. O ni o di ọdun meji ti omọ na ti ngbe odọ on ki o to ku yi.

Ọga Olukọ Oniweẹri aiyederu wẹwọn ọṣu mẹfa

KANO.

NI ọjọ Iṣegun ti ise ọjọ kejilelogun ọṣu yi ni Adajọ Kotu Kekere Kano so ọdaran kan ti nje Benson Ogbona, Oga-oluko (Headmaster) Ile-iwe Methodist kan ti ngba ponun mefa osi si ẹwọn osu mẹfa, nigbati o jẹbi ẹsun pe o fi iwe-ẹri aiyederu onipo keta (Grade III Teacher) ati iwe iyin aiyederu wo ise oluko, o si tun gba ponun mẹtalelogun (£23) lọna eru.

Aman Adesina, Alamojuto Ile-iwe Methodist ti o mba a ṣejọ so fun Adajọ pe nigbati on nse ibẹwo awọn ile-iwe kakiri ni Jos ni ọdaran na ko iwe iwase pelu awọn iwe-ẹri wa fun on, on si gba a ni oluko agba si ile-iwe Kano, Igbẹhingbẹhin ni on to wa sẹsẹ mo pe, iwe-ẹri oluko onipo keta ti o wipe on gba lati Ile-iwe Ekọse Oluko ni "Teacher's Training College, Ihie" iwe aiyederu ni.

Odaran na ni olukọ agba ti o ntanwo-ọṣu fun awọn oluko nipa bẹgi o fowọ si iwe isanwo kan fun ponun mẹtalelogun ti ko le so bi owo na ti ṣe rin. Nigbati Adajọ si bere lowọ odaran na pe, kini ẹjọ ti o fe ro, o ni on gba pe otito ni on se gbogbo ẹsun wọnyi. Ki Adajọ jowọ mase je on ni iya pupọ.

Matẹsun ṣe ẹyẹ ikomọjade

Aworan awọn yi ni ti Ogbẹni ati Iyaafin Y. A. Matẹsun ti nwọn ngbe 27, Princess Street, I'Eko nigbati nwọn se aṣeyẹ ikomọjade omobirin ti Olorun fi ta wọn lọre, nwọn si ṣọ omọ na ni Faosat. Omọ na ni nwọn gbe dani nihin aworan yi. Diẹ ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni Oloye Jagun Matẹsun Ijebu-Ode, Alhaji B. A. Sulemọn, Alhaji N. K. Ladejobi, B. A. Kasim; B. A Ogunfọwọkan, S. Ọshinowọ, L. Ladele; Iyaafin Oshikomaya; G. A. Ademosu ati A. O. Abdul.

MINISTRY OF EDUCATION, WESTERN REGION

VACANCIES FOR WORKSHOP ASSISTANTS

Applications are invited from suitably qualified candidates for the posts of Workshop Assistants in the following trades:—

1. Sheet Metal
2. Wood Machinist
3. Fitter Machinist
4. Blacksmith and Welder
5. Bricklayer

Scale of Salary: Scale F. 1, 2, 3.

QUALIFICATIONS:—

Applicants must have served an apprenticeship in their particular trade and have had subsequent satisfactory experience.

METHOD OF APPICATION:—

Applications should be addressed to the Permanent Secretary, Ministry of Education, (Finance and Establishments Division), Ibadan, so as to reach him not later than Monday, 25th August 1958. Applications from candidates in Government Service should be submitted through the Head of the applicant's Department and be accompanied by a Confidential Report on the appropriate form.

MINISTRY OF EDUCATION, WESTERN REGION.

VACANCIES FOR TECHNICAL INSTRUCTORS

Applications are invited from suitably qualified candidates for the posts of Assistant Technical Instructor-in-Training at the Government Trade Training Centre, Ilaro, in the following trades:—

(i) Motor Vehicle mechanic
(ii) Electrical Installation
(iii) Carpentry and Joinery
(iv) Cabinet Maker

Scale of Salary:— Scale C (T) 1, 2 — £288, £318, £348; £408 — 18 — £468 — 24 — £528; £201 — 24 — £642, £714, £744.

QUALIFICATIONS:—

Applicants must have served an apprenticeship in their particular trade and have had subsequent satisfactory experience. They must also have passed the Intermediate City and Guilds Examination in their trade.

METHOD OF APPLICATIONS:—

Applications should be addressed to the Permanent Secretary, Ministry of Education (Finance and Establishments Division) Ibadan, so as to reach him not later than Monday, 25th August, 1958. Applications from candidates in Government Service should be submitted through the Head of the Applicant's Department and be accompanied by a Confidential Report on the appropriate form.

EYI NI ỌJỌ AWỌN ỌJA ILẸ WA.

Ọjọ Aje 28th July (Monday)

Ilu.	Oruko Awọn Oja
Eko ati agbegbe rẹ	Oyingbo.
Abẹokuta.	Ijoko, Iberẹkodo, Asu, Wasimi.
Ibadan.	Olode, Ogunjana, Lagun, Orile-Imo.
Ijebu.	Aiyepe, Ṣagamu, Ita-Oṣu, Ogere, Imodi, Isara.
Ijesha.	Irolu, Ita-Iloti, Itele, Oyingbo, Ijebu-Ijesha, Ibodi, Ibode, Kajola, Oluwa'da Imesi-Ile.
Ondo ati Eti Odo.	Abigi, Aiyeotro, Oka, Ilara, Epẹ.
Egbado.	Alagba, Ilaro, Sunwa, Iboro.
Ogbomoshọ	Obada, Gambari.
Ekiti.	Ilogbo, Oke-Aiyedun, Idogun
Ibinni	Eke.

Ọjọ Iṣegun 29th July (Tuesday)

Ilu.	Oruko Awọn Oja
Eko ati agbegbe rẹ	Obun-Eko.
Abẹokuta.	Atan, Agbado, Ifọ, Itoku, Kobapẹ Isaṣọ, Odẹda, Ibara, Mowe.
Ibadan.	Ijaiye-Orile, Iressi, Obada, Ẹgbẹla, Oyedeji.
Ijebu.	Ilishan, Odogbolu, Atan Imope, Ishan, Isara, Imodi, Akẹsan.
Ijesha.	Ilaṣẹ, Epẹ, Iloba, Iperindo Imuroko, Erinmo, Esa-Oke. Lode-Idoka, Otan, Eti Oni.
Ondo ati Eti Odo.	Agirifọn-Ilutitun, Odolomu, Igbotako, Ileoluji, Obunkekere.
Egbado.	Aiyetoro, Tata Randu, Ado-Odo.
Ogbomoshọ	Iressa-Du, Arolu, Ẹgbeda, Jabata, Oke Imale.
Ekiti.	Egosi, Odo-Aiyedun- Okemẹsi.
Ibinni.	
Delta.	Kokori.

Ọjọ 'Ru 30th July (Wednesday)

Ilu.	Oruko Awọn Oja
Eko ati agbegbe rẹ	Mushin Badagry.
Abẹokuta.	Otta, Abalabi, Ṣodẹkẹ, Owode.
Ibadan.	Omida, Ilawọ, Owowo, Obafẹmi.
Ijebu.	Oja-Oje.
Ijesha.	Ikẹnnẹ, Okunọwa, Erunwọn.
	Omu, Ago-Iwoye, Isara.
	Ijebu-Ijesha, Oṣu, Itagu, Idoko, Iloko, Odogbo, Owode, Idoka.
	Ilare.
Ondo ati Eti Odo.	Ishua, Aye, Erinkẹta, Agbabu.
	Igbogi, Arowona Idofin.
Egbado.	Ilobi, Igbogila, Ijoun, Imaṣa.
Ogbomoshọ	Araromi, Iregba.
Ekiti.	Erẹkẹsan.
Ibinni.	
Delta.	
Igbajọ.	Iloro.

Ọjọ 'Bọ 31st July (Thursday)

Ilu.	Oruko Awọn Oja
Eko ati agbegbe rẹ	Agege, Ikeja.
Abẹokuta.	Lafẹnwa, Obada, Oba Kajola
	Ajegunle, Idogo, Ogunmaki Itori.
Ibadan.	Lalupọn, Ibuko
Ijebu.	Isara, Imodi, Ibẹfun Atikori.
	Imushin, Ijesha-Ijebu, Mamu
Ijesha.	Ipara, Mojoda.
	Esa Oke, Iwara, Ejioro Odo, Ibokun, Esa Odo, Ibala.
Ondo ati Eti Odo.	Igbo-Egunren.
Egbado.	Idi-Omi, Lasilọ, Igai Okoto, Atta
Ogbomoshọ	Oko
Ekiti.	Ifaki.
Ibinni.	Uromi.
Delta.	

Ọjọ Eti 1st August (Friday)

Ilu.	Oruko Awọn Oja
Eko ati agbegbe rẹ	Oyingbo, Ejirin.
Abẹokuta.	Ijoko Iberẹkodo, Asu, Wasimi, Ṣodẹkẹ.
Ibadan.	Ogunjana, Lagun, Sagbẹ, Olode.
Ijebu.	Aiyepe, Ṣagamu, Ita-Oṣu, Ogere, Irolu, Itele, Ita-Oloti, Agbọwa, Imodi, Isara.
Ijesha.	Ijebu-Ijesha, Ibodi, Bode, Kajola, Oluwa'da, Erẹkẹta, Imẹsi-Ile.
Ondo ati Eti Odo.	Oka, Ilara, Abigi, Aiyetoro, Epẹ.
Egbado.	Alagba, Ilaro, Sunwa, Iboro, Jigga.
Ogbomoshọ	Obada, Gambari.
Ekiti.	Ilogbo, Oke-Aiyedun, Idogun.
Ibinni.	Eke.

Ọjọ Abamẹta 2nd August (Saturday)

Ilu.	Oruko Awọn Oja
Eko ati agbegbe rẹ	Obun Eko, Ikosi (Epẹ).
Abẹokuta.	Atan, Agbado, Ifọ, Itoku, Isabọ, Odẹda, Ibara, Itori, Oja-Iro, Siwun, Papa.
Ibadan.	Ijaiye-Orile, Iressi, Obada, Ẹgbẹda, Oyedeji.
Ijebu.	Ilishan, Odogbolu, Atan, Imope, Ishan, Isara, Imodi, Ikosi.
Ijesha.	Esa-Oke, Ilaṣẹ, Epẹ, Iloba Iperindo, Imuroko, Erinmo, Otan.
	Ipetu.
	Odojomo, Igbotako, Ileoluji
Ondo ati Eti Odo.	Obunkekere, Agirifọn-Ilutitun.
Egbado.	Aiyetoro, Tata, Randu, Ado-Odo.
Ogbomoshọ	Iressa-Du, Arolu, Egbeda.
Ekiti.	Egosi, Odo-Aiyedun, Okemẹsi
Ibinni.	
Delta.	Kokori.

Ọjọ Aiku 3rd August (Sunday)

Ilu.	Oruko Awọn Oja
Eko ati agbegbe rẹ	Mushin.
Abẹokuta.	Owode, Otta, Abalabi, Ṣodẹkẹ, Omida, Ilawọ, Owowo, Obafẹmi, Mokoloki, Orile-Imo, Geleodun.
Ibadan.	Oja-Oje.
Ijebu.	Ikẹnnẹ, Okun-Owa, Eruwọn.
Ijesha.	Omu, Ago-Iwoye, Isara.
	Ijebu-Ijesha, Oshu, Itagun, Odogbo, Iloko, Ipetu, Owode Idodo, Idoka, Ilare, Ijeda.
Ondo ati Eti Odo.	Agbabu, Igbogi, Ishua, Erinkẹta, Arowona, Idofin.
Egbado.	Olorunda, Kajola, Ilobi, Eredo.
Ogbomoshọ	Araromi, Iregba.
Ekiti.	Erẹkẹsan.
Ibinni	Osele.
Igbajọ.	Iloro.

Ọjọ Aje 4th August (Monday)

Ilu.	Oruko Awọn Oja
Eko ati agbegbe rẹ	Agege, Ikeja, Ebute Ero, Ojo, Ajido.
Abẹokuta.	Lafẹnwa, Obada, Oba Kajola, Ajegunle, Idogo, Ogunmaki, Itori, Omu-Ajoyinre, Obanisunwa, Ajura.
Ibadan.	Ibuko, Lalupon.
Ijebu.	Ibefun, Atikori, Imushin, Ijesha-Ijebu, Isara, Imodi, Ipara, Mamu Mojoda.
Ijesha.	Esa-Oke, Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Esa-Odo, Ijeda, Ikeji.
	Ibala, Odo.
Ondo ati Eti Odo.	Igbo-Egunren, Atijere, Oni, Ebiwo.
Egbado.	Idi-Emi, Ibeshe, Lasilo, Atta.
Ogbomoshọ	Oko.
Ekiti.	Ifaki.

Etiṣe ti a ko fi gburo onilu-faaji mọ?

INU mi yio dun pupọ lati ṣe ibere kekere yi, ibere mi na ni pe kinise ti a ko fi gburo oro re Ogbeni Samuel Ayandeji Onilu-faaji ninu Iwe "Irohin Yoruba" to be e mọ gegebi ti atijọ? Nigbakan ri gbogbo nkan ti o ba sele ni Oke-Okun, paapa ni Accra ni o ma a nfun ni ni irohin re, ṣugbọn a ko gbọ o tobe e mọ.

Laipe yi mo ri i ka ninu Iwe "Irohin Yoruba" pe nigbati Ogbeni Samuel Ayandeji Onilufaaji pelu awon elegbere meji kan nti ilu won bo lati Ogbomoshọ wa se ibewo Olotu, inu wa si dun fun irohin na ti a gbọ.

Irohin gbigbo nipa re ko dabi ki a ma a gboro lati enu on paapa bi irohin Oke-Okun ti nlọ si nisisiyi, tabi ti Ominira Ijoba Ghana ni o ka arakunrin na lenu ko ti a ki i fi gburo re. Nitorina ti o ba je ni Accra lo si wa ki o jeki a gburo on o.

Oro mi ko ju bayi lọ, Olotu, mo dupe aye ti e gba mi.

Emi ni,
JACOB O. OLUREBI.
Yobo Village,
via Abalabi Station.

FUN EREE (KIDNEY) RẸ NI OKUN

MA A GBADUN BI OMODE—Ki O SI DABI OMODE

Ko si ohun ti o nso okunrin tabi obirin di arugbo ju aisan ati irora ti aisise deede Eree (Kidney) ngmu wa lo. Eyi ni o ngmu o se aisan Ito rukuruku, Didaji, loru, ki ito ma a jo o nidi, ki iho ile-ito ma a hun o, Oyi, Lakuregbe, Ebin didun, Ojugun nro ni Ibaaba loju. Orunkun wiwu, ki agbara dinku ati beebee lo. CYSTEX yio ran o lowo lati so eje re di akotun kuro ninu omi-aisan ati oro ti o nwo si inu gbogbo awon isepo ati isan ara re. Larin wakati merinlelogun ni CYSTEX yio fi pa gbogbo kokoro-aisan ti o wa ninu Eree (Kidney), yio fun awon Eree (Kidneys) lagbara a si le gbogbo omi-aisan ati oro jade. Ra CYSTEX lowo apoogun ti o ba ri, lori adehun pe yio mu o lara da tabi ki o gba owo re pada. Ta sasa nisisiyi! Larin wakati mokanlelogun ara re yo ya, yio si wo o san patapata larin ose kan.

Cystex

fun awon Eree (Kidneys) Lakuregbe, Ile-Ito.

CLASSIFIED ADVERTISEMENTS

FOR SALE

TYPEWRITERS — from £7 10. 0. Ask catalogue. M-SE LTD 53, Museum Street, LONDON W.C.1

ENVITON

REJUVENATES you. Revives you. Gives capacity for endurance, vigour, brightness and fortifies the tissue. Price: 13/6d. THE GERMAN MEDICINE STORES, 12, Clifford Street, Ebute-Metta.

Ija Ẹgbẹ Alakukọ si ngbona giri-giri larin ara wọn

EKO.

NI ọjọ Aje ti ọse ọjọ kọkanlelogun osu yi ni Oloye Festus Okotie-Eboh so pe iwe ti Dokita K. O. Mbadiwe gbe jade ninu ipade Egbe Oniwe-irohin pe awọn fi owọ si i ri inu osu kerin odun ti o koja yi pe "Azikiwe ni lati lọ" ki ọse eda iwe ti awọn fi owọ si ni o gbe jade, o ni iwe aiyederu flan ti awọn ko fi owọ si ni o gbe jade ti o si so asopọ rẹ mọ iwe ti awọn ti fọwọsi ni iyana ọtọ.

Ni ọjọ keji ni Oloye Kọla Balogun si tun da Okotie-

OLOYE KỌLA BALOGUN

* * *

Eboh lohun ọrọ rẹ ti o si ọe ikede idahun na fun gbogbo enia gbọ pe kosi otitọ ninu ọrọ ti Oloye Okotie-Eboh so rara, o ni Okotie-Eboh gan an ni Olori alatako Azikiwe pe gbogbo ọna ti Azikiwe ndari Egbe Alakukọ si ko dara rara, ọna ireọile ni o ndari Egbẹ Alakukọ si.

O ni totọ iwe ti awọn fi owọ si gan an ni Dokita K. O. Mbadiwe gbe jade fi han awọn Egbẹ Oniwe-irohin ninu ipade ti o ọe pelu wọn ni ọse ti o koja. O ni inu tile bi Okotie-Eboh to bẹ ge ẹ ti o fi pinnu lati fi aye akapo Egbẹ Alakukọ sile, o ni awọn ni awọn fun un ni suuru pe ki o ma ọe ọe bẹ ẹ.

O ni eru mba Oloye Okotie-Eboh ti o fi wa nso nisisiyi pe aiyederu eda iwe ni Mbadiwe gbe jade ti o nso pe awọn ti fọwọ si pe "Azikiwe ni lati lọ", o ni kosi ọrọ otito kan ninu alaye Okotie-Eboh rara.

Balẹ Abule Odogo

Lati oju ewe kini

Oegebi ọlopa na ti ọe rojo niyi:—O ni awọn ri Garuba Sokoto ti o nsiẹ agbarooko l'abule Ebutero o wa fẹjọ sun awọn pe nigbati Asiru Asode-oru ri on ni o ba mu on lọ siwaju Balẹ Abule Odogo pe ọlọsa ni on. Balẹ na ba paọe pe ki awọn odaran yi mu on lọ sinu igbẹ na ni on ba jabọ lowọ won ti on fi mu ẹjọ won wa si odo awọn ọlopa Ilaro.

Nigbati ọlopa rojo tan ni Ogbeni Olayiwola Oshinuga ti ọe agbẹjọro awọn odaran na so ni Kotu pe, ki ọe bi ọlopa ti ọe rojọ yi i oran na ri gan an, o ni nigbati Asiru asode-oru ri Garuba Sokoto loru, ti o si ni ifura si i wipe ọlọsa ni, ti o si mu u wa siwaju Balẹ na, ni Balẹ na ba paọe fun asode ati awọn enia ti o wa pelu re pe ki nwon mu u lọ si odo awọn ọlopa, ki nwon si so bi oran re na ti je fun ọlopa. Nigbati nwon nlo ni oju ona ni okunrin Hausa na sa mọ won lowọ nitori ki nwon ma ba a ri i basejọ.

Nigbati agbẹjọro awọn odaran na soro tan bayi, ni awọn odaran na ba si so fun Adajo pe awọ ko jebi ni Adajo ba fi ye gbigbọ ẹjọ won si ojo kefa osu ti mbọ yi, sugbon o ni ki awọn odaran na si wa ni itimole titi ti ọjọ na yio fi pe.

CLASSIFIED ADVERTISEMENTS

A tun gbe de

IWE Egbogi Iwosan 10s, 6d., Itan Ifa Agbigba ati Yanrin titẹ 6s. 6d., Kuranị Esu Mẹwa ti a tumọ si Yoruba 8s. 6d. Postage 1s. E fi owo ranse si ESAN KOGBOGUN SERVICE, 8 Idumagbo Avenue Lagos, Nigeria.

Ijafara lewu

Ase ikede yi fun gbogbo awọn Onibara wa pe diẹ ni awọn iwe ti a polowo silhin ku. Nitorina ijafara lewu o. 6th & 7th Books of Moses L'ede Yoruba 15s., Kokoro 6th & 7th Books of Moses 20s., Iwe Asiri Oba Dafidi 20s., Iwe Egbogi fun Agan ati Iwosan Jedijedi eleje 2s. pere etc. Kowe si Manager—36, King George Avenue, Yaba, Nigeria abi 83, Idikan Road, Ibadan.

THERMOGENE alagbara, Egbogi ipara atata o kuku
DARAPUPO fun esanri
DARAPUPO fun irora
DARAPUPO fun ara gigan, fifọ ati finfọn
DARAPUPO fun ori fifọ ati aiya didun.
Enikeni mo pe THERMOGENE ni o dara julọ

O wa ninu awọn pangolo ati ide

THERMOGENE

IPARA AGBARUN

A ma a ṣe iwosan, o tu ara, a si ma a mu ara lọ-wọwọ

ORIKI BAMWO

Bamwo de alajela omode, agbomola bi orisa. Akokoluko ogun ti nda'molẹkun igbona, atata ogun ti np'otutu lẹ wazwara. O s'abiku d'ikugbagbe, o y'ọmọ ti nh'ehin lore. Iko ri i sa. Iba ko o l'ona ta giri. Aiperi ri i d'ekun iyọnu. Olugbala l'omọ ti nyagbe orin. O k'apa inuwọ, o lu jedijedi l'alupa; gbogbo abiyamo nyọ seṣẹ. Eia ri i, o ro'ju. Orere ri i o na 'gbe bora. Eyi npa'lemọ lodileṣọ. Ọrẹ Ikoko, Kosemani awọn abiyamọ, eni araiye njijadu ra. Wa ra a lodo wa: Igo kekere 2s. 6d., Igo nla 4s. 6d. Owo-oko 1s. 6d. Kowe si wa fun arapo lati gba ẹdinwo.

The Egba Trading Aradan Stores

144, Denton Street, IR. Denton Bridge St., P.O. Box 2, Ebute-Metta. 46, Victoria Street, Lagos ati New Motor Park, Ibadan.

Read this list of popular titles

'HMV RED LABEL

JZB. 1000 — Bowo Fun Oluwa/Owo Niyi Omo Laso
" 1001 — Ibukun Oluwa Ko/Baba Olore Gbawa Kari Wa
Baptist Church Choristers, Yaba.
JZB. 1002 — Yedenu Ajawhi/Oyugbo Tonayin
" 1003 — Mina Jerenude Pon/ Mikan Fadi
" 1004 — Atono Nado Na Woyi/Alo Wa Nude Towẹ
Dranvondun Amandekpe & His (Jegbele) Band.
JZB. 1005 — Meteta Lanfe/Yoyo Lenu Araiye
" 1006 — Okeya/Abewo Oba Ilu Oyinbo
S. O. A. Ladipo & His (Koranle) Group

HMV RED LABEL

JZB. 1007 — Aka-Ojindo/Mamma Lenboye
" 1008 — Owe Tagbatewe/Wati Asimolowo
" 1009 — Ilori/Ologbon Aiye
Kelani Yesufu & His (Sakara) Band.
JZB. 1010 — Igbomina/Tafa Sawo
" 1011 — Waka Odolaiye/ Babatunde Omu
" 1012 — Sonmonri Yeye/Ewi Odolaiye
Odolaiye Aremu & (Pankeke) Band.

OBTAINABLE FROM:—

1. Y. A. BILESANMI — 87, Victoria Street, Lagos.
2. ANIMAWUN STORES — 34, Victoria Street, Lagos.
3. SALAWU AREMU — 73, Victoria Street, Lagos.

Sold by all the best stores

"HIS MASTER'S VOICE" Yellow Label RECORDS

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

Printed and published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd., 3/7 Apongbon Street, Lagos. (Editorial and Advert offices). Telephone 21675. Fun owo "Irohin Yoruba" odun kan: Eko—sile mejo sti kobo mejo (6s 3d). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Oyan—sile metala (12s.). Olotu S. M. Ademuyiwa, 9, Chapel Street, Lagos.